20 NOV 1965

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA
No 1,560 TUESDAY NOVEMBER 16, 1965 (2D)

## Ile Igbimo Asofin Ila Orun Fe Se Ipade

ENUGUN:— Ninu irohin kan to de ile ise wa ni ojo Abameta ti ise ojo ketala oṣu yi ni a ti gbọ wipe awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria yio bẹrẹ ipade Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba na ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ ketalelogun oṣu yi.

Irohin lati ile iṣẹ Akowe agba fun ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria fi ye wa pe gbogbo awon ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ na ni nwọn ti kọ iwe fun lori ipade ti nwọn yio ṣe ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ ketalelogun oṣu yi.

Oniwe irohin wa to wa ni Enugun Ipinlẹ Ila Orun Naijiria fi ye wa ninu irohin rẹ pe on ko ti gbọ nipa ohunti awọn ọmọ Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ na yio ṣe ipade le lori tabi ohun ti nwọn yio jiroro le lori ninu ipade ti nwọn yio ṣe ni ọjọ na.

### Alhaji Masha Sọ Pe :

# EGBE OLOPE ATI ALAKUKỌ NI YIO ṢE IJỌBA

EKO:- Ninu irohin to jade lati ọwọ Alaga ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko tẹlẹ Alhaji A. F. Masha ni o ti ṣe alaye pe ẹgbẹ on ti iṣe ẹgbẹ Afẹnifẹre yio sise papọ pẹlu ẹgbẹ Alakukọ ninu ile Igbimọ ti Ijọba ibilẹ ilu Eko lorukọ ẹgbẹ ajumọsepọ UPGA ati pe awọn ki yio ya ara ṣọtọ rara.

Alhaji Masha tun dupẹ lọwọ awọn enia ilu Eko lori isowọpọ ti awọn enia na ni pẹlu ẹgbẹ Afẹnifẹre lati le da wọn pada si ijoko eto akoso Ijọba ibilẹ ilu Eko eyiti nwọn ti ṣe akoso rẹ koja.

O tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ pe ẹgbẹ Afẹnifẹre yio ṣe ohunti o tọ ti o si yẹ si ilu Eko ati awọn enia ilu na lati le jẹki o jẹ orukọ ti o tọ si ilu na ni orilẹ ede Afrika.

Ninu awọn Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre to sọrọ lori abayori idibo si ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko eyiti ẹgbẹ Afẹnifere bori ni Olori ẹgbẹ Afẹnifere ni ile Igbimọ apapọ Ijọba.

Ninu ọrọ Oloye O. B. Akin Olugbade ni o ti ṣe alaye lori gẹgẹbi ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ṣe lori idibo si ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko Oloye Akin-Olugbade tun ṣe alaye pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ si ti fi eto ofin han lori ọna idibo eyiti awọn ẹgbẹ na ṣe lọna eto laisi madaru tabi iwa jibiti ninu eto idibo ninu ọna eto ofin ni ilẹ Naijiria.

Oloye Akin Olugbade tun ṣe alaye pe awọn ẹgbẹ mejeji yio ma ṣe eto akoso Ijọba ibilẹ ilu Eko lọna eto ẹgbẹ ajumọṣe eyiti iṣe ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA).

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe ẹgbẹ Afẹnire ko aye ijoko marundinlogoji (35 seats) ninu idibo eyiti ẹgbẹ Alakukọ si ko aye ijoko meje.

Oloye Akin Olugbade tun ṣe alaye pe lẹhin ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ NNDP ati ẹgbẹ Olomi (NPC) ṣe eto ipolowo ibo si Ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko ti awọn Adibo si le wọn jade ninu ile wọn lo mu awọn ẹgbẹ na sọ pe awọn ko dibo mọ.

Oloye Akin Olugbade tun ṣe alaye pe eleyi lo mu tete yara da awọn ẹgbẹ Olomi (NPC) ati ẹgbẹ Ọlọwọ (NNDP) loju pe awọn enia ilu Eko ko si lẹhin ati pe ohun ti o tọ si wọn ni lati tete jẹwọ ki nwọn maṣe dibo mọ.

Ni ipari ọrọ rẹ Oloye O. B. Akin Olugbade tun ṣe alaye pe eto idibo si Ile Igbimọ ti Ijoba ibilẹ ilu Eko na ti iṣe idije larin ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ si jẹ idije eyiti iṣe nipa ọna ọrọ eyiti ẹgbẹ mejeji iṣe.



**Alhaji A. F. Masha**
ALAGA IJỌBA IBILẸ EKO

Oloye na tun ṣe alaye pe eto idibo na larin ẹgbẹ mejeji si lọ ni ọna ẹtọ laisi ija tabi edeaiyede larin awọn ẹgbẹ meje ji.

Oloye Akin Olugbade tun ṣe alaye pe lori eto ọna iṣelu ni orilẹ ede Afrika ni nwọn gba ṣe eto idibo na ati pe awọn enia to dibo si tẹle ọna eto ibo ti nwọn gbe ndibo ni ilẹ Amerika tabi ni ilẹ Gẹẹsi.

Ninu eniti o tun sọrọ lori eto idibo na ni Oloye Fred Anyiam Alakoso eto Irohin fun ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA) ni ilu Eko ti o tun jẹ ẹkan ninu awọn Aṣoju ti nwọn dibo fun ninu idibo si Ile Igbimọ ti Ijọba ibilẹ ilu Eko.

Oloye F. U. Anyiam tun ṣe alaye pe gẹgẹbi nwọn ti ṣe idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba ibilẹ ilu Eko lọ si tẹ on lọrun ati pe awọn enia ilu na dibo lọna ti o jẹ wipe o tẹ on lọrun a t i p e awọn enia na dibo gẹgẹbi o ti ṣe wu wọn.

Oloye F. U. Anyiam si jẹ Aṣoju ẹgbẹ Alakukọ ni Ward E 7 ati pe on si ni o bori ibo na ti o gbẹyẹ lọwọ ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre Ọgbẹni O. Abinbọla ti nwọn jijọ fi aga-gbaga.

Eyiti o jẹ iyalẹnu ju lọ ninu ọrọ eto ibo na ni aye ijoko eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre to bori rẹ ju eyiti nwọn ti bori lasiko idibo ti ẹdun 1962.

Ninu ọrọ Alaga Igbimọ Amuẹẹ ṣe ẹgbẹ alakukọ ni ilu Eko Oloye Adeniran Ogunsanya ni o ti ṣe alaye pe aye ijoko ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ko lori idibo si Ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko si jẹ ohun ti o yatọ si gbogbo ibo ti nwọn ti di kọja.

Oloye Ogunsanya tun ṣe alaye pe ibo ti awon enia ilu Eko di fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu idibo to kọja yi si ju gbogbo ti nwon ti ndi kọja lo Oloye Ogunsanya tun ṣe alaye pe ohunti olori ẹgbẹ Afẹnifẹre yio gbo irohin fun ara rẹni lori aye Ijoko ti ẹgbẹ rẹ ko ninu idibo na.

O tun ṣe alaye pe ohunti o wu enia lori lati ri pe eto akoso Ijoba Ibilẹ ilu Eko si tun wa lati ẹgbẹ itẹsiwaju U P G A.

Oloye Ogunsanya tun ṣe alaye pe lorukọ ẹgbẹ Alakukọ ni ilu Eko o ti on ba ẹgbẹ Afẹnifẹre yọ pe nwọn bori ibo si ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ ilu Eko

Ninu ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Eko ni wọn ti ṣe alaye pe awọn dupẹ gidigidi lọwọ awọn adibo ilu Eko pe nwọn dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre wọle lati le jẹki nwọn ṣe eto akoso Ijọba ibilẹ na lekeje ati pe tun ida niloju ti awọn enia na ni ninu ẹgbẹ na ati igbẹkẹle ti wọn tun ni olori ẹgbẹ na olo jẹ Ọbafẹmi Awolowọ

Wo Oju Ewe Kẹfa

# Eyi Ni Ẹda Ọrọ Ti Ikoku Kọ Ranṣẹ Si Naijiria (Apa 2)

"Awọn Oyinbo to nda ile wa ru yi wa ninu ẹgbẹ Alasowọpọ eyiti Amẹrika, Gẹẹsi Iwọ Orun Jamani, Israel, Holland ati Faranse jẹ alajọpọ nla ninu ẹgbẹ Alasowọpọ na O le ri ia ti iranlọwọ lori awọn ọgbọn ori wa. A korira Oloye Akintọla, ṣugbọn a si nji-yan pe, Ọlọla Balewa bẹru Ọlọrun o le ṣe ododo idajọ larin wa ati Oloye Akintọla. A ti gbagbọ pe, ipo ti Oloye Akintọla wa ni Ọlọla Balewa wa ati ipo ti Ọlọla Balewa wa ni Oloye Akintọla wa pẹlu.

"A ṣetan lati da ẹiyẹ si Ọlọla Ahmadu ti a si nsọ otito inu wa fun awọn asoju Gẹẹsi Iwọ Orun Jamani awọn asoju ilu Amẹrika Israel ati awọn ilu miran Ati gbagbọ pe Ahmadu-Balewa Akintola Ijọba won wa labẹ ẹsẹ awọn ti mo ti da ruko yi. O dabi ẹni wipe a nfi ẹjọ ọmọ odo ti oga rẹ ran se ti o nse iṣẹ ti oga rẹ ran sun Ọga rẹ ti o ran nṣẹ o ma pa enia lẹrin o!

A ti ṣe aṣiṣe sẹhin nitoripe awọn ti ko to ni a fi inu han igbẹkẹle wa kosi lọwọ Ọlọla awon ọmọ alade biko ṣe awọn mẹkunnu a ko gbo do tun ṣe aṣiṣe ti ẹhin mọ. Bi a ba ti ṣẹgun awon ota wa tan. Ilẹ Naijiria yio tun ma a ja fitafita lati ṣẹgun awọn ajoji ati onigbowo nwon awon ẹgbẹ itẹsiwaju ti agbara won lase ko ogun agbaiye keji to pari. Awon enia nla ti nja fun ilẹ wa ni awon bi Herbert Macauley Nnamdi Azikiwe, Michael Imoudu Ọbafẹmi Awolowo Bode Thomas Anthony Enahoro awon ẹgbẹ ti o njẹ Zikist ati awọn enia miran.

"Awon Balewa awon Ribadu Shetima Kassim won wa ni apa kan ni orisirisi ona nwon sin oga won ti o jẹ Oyinbo nwon se iṣẹ won boya bi Asoju tabi Alaga Igbimọ tabi ti nwọn jẹ omo Igbimọ ti nwọn si njiṣẹ fun oga won

"Kini o tun ku, ni tooto a gba Ominira ni odun 1960 a ko gba ominira nipa ibo didi nitootọ a ndi orisirisi ibo

Omiran rorun nigbati a ti san owo fun aja ilẹ ipa ni ati ṣe atpo ni idalẹ ẹwọn ildọ ati orisirisi ẹjọ pipe. Ominira ti a gba ni 1960 ko yanju rara bi a ba kiyesi iselu wa l ti 1945 titi de 1960 ọrọ mi yio ye yin pe a nfi akisa aṣọ lẹ aṣọ tuntun nitoripe iselu wa wa lọwọ awọn kan.

"Ominira wa, wa lọwọ awọn kan lọna kan osi tun wa lọwọ wa lọna ẹtọ miran ani lati tun ma ja fun ominira lati parọ Bello. Balewa ati Akintọla ki a si fi ojulowo ọmọ ilẹ Naijiria to ni ẹmi ati sin ilẹ wa titẹtifẹ rọpo wọn.

"Nisisiyi ati mo ọta wa bawo ni a ti nmura si ija na to. ibere wa pe ba o ni to ṣe ja ija miran ni o kan nisisiyi.

"Awọn ẹkọ ti a nkọ ko fi ọn anfani han wa rara abẹ lẹlẹ ni o nja ba, awon enia kan tun jẹ ohun elo fun abẹtẹlẹ yi, awọn kan wa ti awọn kan ti ra wọn, awọn ni o nmu enia b nu ati ọda lẹ n wọn. Wiwa ti ile ẹjọ eto Ijọba a i bẹ lọ wa ni lẹ wa lo i sọ wipe o si tun ni eṣo Ijọba idẹra.

"Ọna ti anfani Ijọba idẹra yio fi a, ẹburu ni o jẹ ati ba Ijọba idẹra na jẹ pa tapata agbara Ijọba na ni ọmọ og n, ọlọpa iṣẹ jijẹ la bẹlẹ ati ifaramọ awọn ala gbara to wa ni idalẹ.



**Oloye Ọbafẹmi Awolowo**

Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

"Ako le lọ nu alaṣyọri gbogbo kan ti nṣele yi papa lati ọdun 1959 ti a dibo wa ti kun ku irẹsẹ nigba ti a tun dibo miran ni ọdun 1954 si Ile Igbimọ Aṣofin apapọ Ijọba eyiti a di si Ipinlẹ Iwọ Orun ni iwe idi bo ya yẹyẹ nigbati awọn enia fẹ ko iwe aidara yi nwọn ko ri ... nibi ti nwọn ti ... gbogbo agba a ibi iṣẹ na ... bẹ awọn oṣelu.

"Nisiyi ona wa dibi ẹgbẹ koro iu Ijọba yẹyẹ larin lọ yi ko le yipada si Ijọba to baje ti ao si tun ma a sọ ibo si u areti.

"Kini a liṣe bayi? Njẹ o wa yẹ ki a hu iwa aidara? Idahun mi ni bẹkọ, ẹgbẹ wa ko gbọdọ hu iwa de bi pe ao hu iwa aidara lati ọdọ Ogidi de ọmọ ẹhin ni yio ma a ja fun alafia orilẹ ede yi.

"Ọna kanna to si sile fun wa nipa igbiyanju enia Kakaki awọn oṣelu ...ẹ ma a fọnnu kakiri maa hu iwa ti kotọ ki ibo didi ba de ohun ti o yẹ ki a ma a ṣe ni gbogbo igba ni GBOGBO ENIA NIGBAGBOGBO.

"Gbogbo ọna ogun ni a o gba lati ba awọn ọta wa ja ki ako ọja awọn silẹ ki a ṣe iṣọde pe a ko fẹ wọn ki a ko gbogbo iranlọwọ wọn silẹ patapata.

"Asiko ti a ba ṣe awọn nkan wọnyi:- atunṣe nkan miran ni o wa ti pelọpọ enia si ni ipin ninu rẹ eyi ni ọna ti awọn enia yio fi ṣe aṣeyọri dajudaju ao ṣẹgun awọn ọta yi.

"Nisisiyi iyipada to yẹ ki o wa ninu ẹgbẹ wa po a nfẹ ipilẹ tere ti ko o tun ẹgbẹ yi ko le lori ti ao le a tun ẹgbẹ wa na ṣe daada awọn ohun ti a o lo na ni:-

1 Ao tun ete ẹgbẹ wa eyi ti o jẹ ori koko ori kakiri a o si tun mojuto ẹgbẹ wa nigbagbogbo

2 Ao jẹ ki ẹgbẹ wa tanka gbogbo ilu, ile iṣẹ, adugbo, ileto ati igberiko

3 Gbogbo enia ni ao ko jọ bi ẹgbẹjẹg ẹ ti a si ma ja fun idẹra awọn enia

4 Lati agbarijọ ni a o ti ma paṣẹ ṣugbọn ẹgbẹ yio wa kakiri gbogbo Orilẹ-ede yi

5 Kia fi ọran tin asiwaju wa daada ninu awọn ẹka ẹgbẹ wa bi awon mẹkunnu osiṣẹ agbẹ ati bẹẹbẹẹ lọ

"Lọna yi awa yio le ni ẹgbẹ to fi idimulẹ (eyiti yio so gbogbo wa pọ lori ete ẹgbẹ wa) Iru ẹgbẹ yi ni yio so gbogbo ... pọ pẹlu awọn enia eyiti ao le jẹ asiwaju wọn ti a o si maa fi iwe rere lele ti ao tan ma a wa enia ti gbogbo enia yio fi ni ojo ojo awọn ẹ la-sko ti ao tun maa ran aini won lọwọ.

"Mo ni lati sọ nibi pe lati ni ẹgbẹ ti o fidimulẹ gẹgẹbi a ti nṣe ọrọ popọ kokan gbọn ki a ma s fi tolantan ṣe i kan ko le ba iru e ra.

Wo Oju Ewe Karun

# Ile Marun Jona Ni Igbara-Oke

IGBARA-OKE:— Ni ọjọ ọjọ'Bo ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni awọn enia kan tun dana sun ile marun eyiti ọkan ninu awọn ile ti ti nwọn dana sun na jẹ ti Ọgbẹni Okuta Tisafẹ ti iṣe baba Oloye J L Tisafẹ Minista Alamojuto eto irohin fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni ilu Igbara Oke ni ẹkun Akurẹ ati ye irohin tun fi ye wa pe nwọn ko mọ awọn enia to dana sun ile na

Ninu awọn ohunti o jona ninu ina na ni mọto ayọkẹlẹ kan ti iṣe ti Ọgbẹni Ọlajide ọkan ninu awọn adajọ ni ile ejọ ti Ijọba ibilẹ ni Igbara-Oke, mọto akero kan ti iṣe ti Ọgbẹni Popoọla ati mọto ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ kan lo jẹ wipe o jona rau rau ninu ina na.

Irohin lati ọwọ oniwe irohin wa to wa ni ilu Igbara-Oke fi ye wa pe ni alẹ ọjọ na ni iṣẹlẹ na ṣelẹ eyiti o fi jẹ wipe awọn enia to ṣe ijamba na bẹrẹsi kọ orin eyiti o jemọ ti ẹgbẹ oṣelu ki nwọn to dana sun awọn ile na.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe awọn enia kan tun dana sun ile marun miran ti iṣe ti awọn olori ẹgbẹ oṣelu kan ni ilu Ijare ni agbegbe Akurẹ eyiti nwọn ko mọ awọn enia to dana sun awọn ile na.

Ni ilu Agbọwa-Ikosi ni a ti gbọ pe awọn enia kan tun kọlu ọgbẹni Wanabi Adebayọ Adefọla ti iṣe agbẹjọro fun ẹgbẹ Dẹmọ ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi, irohin fi ye wa pe nwọn ko mọ awọn enia to lọ kọlu ọgbeni Adefọla na.

Oniwe irohin wa ti ọrọ na ṣoju rẹ fi ye wa pe ọgbẹui Adefọla lọ wo awọn ẹniti o ngbẹnusọ fun ni ile ẹjọ eyiti o fi jẹ pe awọn jandu ku ọmọ ẹgbẹ oṣelu na fi kọlu ọgbọ ni na titi o fi sa wọ ile kan ni ilu Agbọwa.

Oniwe irohin fi ye wa pe awọn enia na fere yọ oju ọtun ọgbẹni Adefọla silẹ eyiti o fi jẹ pe awọn enia to wa ni ilu na lo si gba ọgbẹni na silẹ ki ọwọ awọn enia na ma ba tẹ.

Awọn enia na si dana sun mọto ayokẹlẹ ti ogbẹni na gbe lo si ilu na to fi jẹ pe nwon ba moto na jẹ debi to le ṣe tunṣe. Irohin fi ye wa pe ki awon olopa to de lu na lati Shagamu ni gbogbo awon enia na ti salo ti awon olopa ko ti awon enia na mu mo.

Awon olopa lo si gbe ogbẹni na lọ si ile iwosan ti ilu Shagamu eyiti o fi jẹ pe ibẹ na ni nwon ti gbe lo si ile iwosan ti Orita Mẹfa ni Ibadan nibiti o ti wa ninu ewu bayi.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe awọn ọlọpa-nu ti lọ si ilu Agbọwa lati Ijẹbu-Ode lori ohunti o ṣẹlẹ ni ilu na ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi lati lọ ṣe iwadi ohunti o ṣẹlẹ na tabi lati leri ninu awọn enia to fa rogbodiyan na silẹ.

Bakanna ni irohin tun de ile iṣẹ wa lati ilu Ipẹru lẹba Shagamu pe awọn Ọlọpa ri ọkunrin kan gbe ninu gọta ni arin ilu na ṣugbọn awọn Ọlọpa tun fi ye oniwe irohin wa to wa ni ilu Shagamu pe nwọn ko ti mọ oruko ọkunrin na ati ibiti o ti wa si ilu. Ṣokoto penpe kan lo wa nidi ọkunrun na pẹlu apa ibọn ni aya rẹ.

Awọn Ọlọpa ti gbe oku ọkunrin na lọ si ile Iwosan ti ilu Shagamu lati lọ ṣe ayẹwo rẹ ninu ile Iwosan na. Awọn ọlọpa si ti nṣe iwadi ẹniti o pa ọkunrin na ṣugbọn nwọn ko ti mọ ẹniti o pa ọkunrin na ati pe awọn Ọlọpa ko ti mu ẹnkankan bayi.

Bakanna ni irohin fi ye wa pe awọn enia kan lọ kọlu Ọgbẹni A. O. Ọdunbọ ti nṣe iṣẹ Olowoele ni a gbọ pe awọn enia na lo kọlu ninu ile rẹ ni ilu kan ti nwọn npe ni ni Shotubo lẹba Shagamu ti nwọn si gbe owo ọkunrin na lọ. Irohin tun fi ye wa pe awọn enia na lọ kolu pe ninu ẹmi rẹ tabi owo ati gbagbo na ki o mu ọkan ni Ọgbẹni A. O Ọdunbọ ba sare jade ti awọn enia si gbe owo rẹ lọ ti nwọn si ba gbogbo ile rẹ jẹ



Aworan oke yi ni ti Awon ile to jona ni Igbara Oke

## Ha! Kini Eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ, A ri o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun.

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ

Three elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orile ede yi.

*DISTRIBUTORS*

**Amos GBENLE & BROTHERS**

34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street. West
LAGOS

## APIAS RHUEMATIC & DRAGES

Jẹ ojulowo hanunhanun egbogi Jamani to lagbara gidigi di fun iwosan "LAKUREGBE" to mba enia ja

Orişirişi lakuregbe ni o wa Lakuregbe Arungun ti o ma nsan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbẹ orikerike danwo kori bi o ti rorun lati lo tabi ki o ma ṣe ayipada ẹsẹ, ara tita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi abi egusi ara wiwo, ako iba abi pipon tabi rirun.

Bi enia ko ba gbajumọ lati toju rẹ lasiko o le so owo pa enia



ATI NI ṢOBU

IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN

## E Ma Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

# Ọde Ile Ifẹ Nigboro Ilu Alọ Apa 5

LATI ỌWO ẸṢO

Nighati awọn ọdẹ ile Ifẹ ri wipe oporo awọn iwin ilu Alọ lo tun mba awọn jagun, nitorina, ki nwọn maṣe je-ki wọn a aa siłẹ. Tohun-tẹnu bi nwọn ti njiroro yi lọwọ bẹni nwọn ngbọ ohun nla kan ti o mbu ramuramu bọ a wipe, ẹni ba le ja ko jade, awọ ẹkun la fi ṣe, bi ohun na ba le orin yi, awọn yoku yio gbe orin na.

Nighati o ṣe ni awọn Abugijẹ Ewe su yọ li oke-re ti nwọn bọwa, Ọdẹ kan si wipe ha! awọn Abugijẹ Ewel ni wọn, ẹ jẹki a yẹra fun wọn! Nibẹ ni Ọdẹ kan ni nwọn npe ni Ọfẹṣẹ meje-ji sọ ko do dahun wipe "Gbangbami ko yẹ agba kini kan ule mi bọwa ko yẹ ọdẹ." Bi nwọn ti nbọ ẹ si nwọn ma ba Ọ no ina li a oran si ina Ologini lo pade ẹkun Iyna ọdẹ lo pade ọ ẹ o lọwọ bọ apo ọdẹ re o yọ ẹda osu ibo a ja de o ti Ile ni ajaju awọn ọdẹ Ile Ifẹ o wipe ẹnyin ẹdi ara abaren tini le mu nyin? Ẹpa na si dahun pe a yali Ọlọrun a fi en a o ṣe si i si ẹda na o ni ki o lọ la awọn abugijẹ ewele na ja ki o si pa wọn.

Loju kanna Ẹdan yi ti bimọ bi iwọn Ẹgba, nwọn mu kondo ati kumọ dani, nwọn si fi ija pẹta nigboro ilu Alọ ariwo ati ẹruku iru eyiti nwọn ko ri ri lo ṣelẹ, gbogbo ara ilu Alọ tun uke abamọ fun pipe ti nwọn pe awọn Ewele Abugijẹ. Lati ọjọ na wa ni awọn Abugijẹ ko wa si aiye mọ nitoripe gbogbo wọn ni Ẹdan ara Abarẹ lapa yanyan.

Ọba Ilu Alọ ti rinṣẹ pe Ina Awọ jogbo, ati orun awọn jogbo, o si ran wọn nisẹ pe ki nwọn lọ sun gbogbo awọn Ọdẹ Ile Ifẹ laiku ẹnikan, Orun bẹrẹ si ran buruku buruku tobẹ ti gbogbo igbẹ ati igbo fi gbina ti ọwọ na si ga soke.

# YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Oni ni oni njẹ, ọjọ pe lo ti o ni lati ṣe ipinnu pataki kan, ire si ni igbẹhin rẹ yio jẹ.

PISCES (Feb 22-Mar 20) Bi o ba lọ si ode to jina, tabi o lo si idalẹ ranpẹ kan, maṣe gbagbe lati tọju awọn ẹbi rẹ ki o ma ba si ijọgbọn.

ARIES (Mar 21-April 20) Igba rere kan yio ṣẹlẹ si ọ ti iwọ yio ri ere a ro tẹlẹ jẹ, tabi ki iwọ ri ẹbun ti o jọju gba ṣugbọn ki o ṣọra rẹ, ni alẹ oni, ki o ma ṣe nkan ijangbọn.

TAURUS (April 21-May 20) Iwọ yio ni itẹlọrun lona gbogbo, alafia ara yio si tọ ọ, idunnu ati ayọ yio wa fun ọ pẹlu ayọ ati idunnu na, yio si ran awọn ẹbi rẹ.

GEMINI (May 21-June 21) Ohun rere kan yio ṣẹlẹ si ọ ninu eyi ti iwọ yio ri ere tirẹ jẹ ninu rẹ lati oni lọ

CANCER (June 22 July 22) Iwọ yio minringindin ninu ọdun kan ti iwọ yio ba awọn ẹgbẹ rẹ lọ. nwọn o si ba ọ di mọ lati ṣe iranlọwọ ati fun ọ.

LEO June 23-Aug 22 Igbadun ati alafia ara yio wa fun ọ, lo iwọ yio si ma ebẹlẹ bi arab .

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Ya iru iṣẹ ti iwọ yio ma ṣe loni, ohunkohun ti o ba si jẹ ṣiṣe, ni iwọ yio ṣe pẹlu irọrun

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Ni owurọ oni, ire kan pataki ni lati kan ọ, ṣugbọn o yẹ ki o simi ni alẹ oni. nitori ki are ma ba de si ọ.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Ọọ gbarag da kan yio si sile ni iwaju rẹ ti yio si mu inu rẹ dun ṣugbọn bi o ba di asale ki o ẹpẹ ki o ma si se fi ijọgbọn kan,

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Gbidanwo ki o si fi awọn aṣọ rẹ o irin kiri ki o si daraya diẹ eyi ni yio mu alafia wa fun ọ.

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Ohun kan ti o ti ngbero lati ṣe ohun ni yio pada di o itọ nitorina ko ma yọ.

# O Ti De Jaburata

Eyi ni lati kede fun awọn Onibara wa pe. Iwe Itumo Ala. Iṣẹ Wiwo, ọjọ ibi Ọmo de lati Ọgun Ajẹbidan alapapo wa nilẹ fun tita nisisiyi, tete wa ra irẹ loni ki o to tan.

Asi tun ṣẹṣẹ ṣe Iwe Itumo Ala miran ati owo Joseph Alala

Irohin ko to afojusa 3/6d pere ni, ẹyọ kan, mejila tabi dosin ni rẹ jẹ 30/-

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9, Iyala Street,
Mushin.



Ọgbẹni J. O. Shoyink

Asi nfẹ awon ti yio ma ba wa ta awon iwe wa na

Tete wa si ọdọ Olotu

POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin


The NEW HOOVER
Washing Machine
Makes Clothes
Whiter and Brighter
It's easier the....
HOOVER way



The NEW HOOVEMATIC washes rinses spins dry 5lbs. of clothes in 4 minutes all in one continuous operation. That's the amazing performance of the new Hoovermatic, a combined Washing Machine and Spin Dryer.

AVAILABLE AT
LEVENTIS TECHNICAL
MARINA — IDDO — IBADAN —
KADUNA — JOS — KANO —
P. HARCOURT — ABA.
and Kingsway Stores.

# Eyi Ni Ẹda Ọrọ Ti Ikoku Kọ

## Lati Oju Ewe Keji

"Işẹ ki i ti o yẹ ki a kokọ şe ni pa ki a yan awọn kan ti yio maa mojuto alafia awọn enia. Awọn ti a ba yan yio maa fi awọn ako-ko kan silẹ lati maa moju-to awọn ohun ti ẹgbẹ ba fẹ şe lati fi ẹgbẹ orilẹ ede wa yi ga pẹlu idẹ a fun gbogbo enia nwọn yio tun maa mojuto awọn oh n inu ẹgbẹ ati ẹkọ lori eto ẹgbẹ na.

"Nwọn ni lati tun ma kọ nipa işelu ala a ati ọna idẹ ra fun işẹ Aje orilẹ ede Nai jiria ati awọn nkan ti e ba yẹ lati fi şe w n yekeyẹ e. Nwọn yio kọ bi awọn kan tişe nfi arawọn şe ọga lọn anikanjọ ọn ja ki a mọ fi ọna ti nwọn yio tun ẹgbẹ nwọn şe h n wọn paapa aw n ti o nba irẹjẹ ip nju ijẹniya abẹtẹlẹ j rẹ u awọn ti nwọn ko ka li ba Belo-Bal wa-Aki t la si i.

"A ni lati reti e iyede l rin ẹgbẹ w bi b ti nli gb ra to bẹni ale a wa yio ma pe si ti awọn enia ibẹ yio ma şu l ona k a to de i ẹ Kenani ẹrişi işi irọ ni nwọn yio ma fi bo iti ju wọn p lu itanjẹ ara rọ won ni Ijọba ti gbogbo ẹgbẹ işelu tabi ki ẹgbẹ meji papo şe Ijọba isọkan ati alafia.

"Awon'aṣiran yio ma fun



**Oloye Anthony Enahoro**

Igbakeji Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

ero ni gbogbo aiye ati ọna ti awon orilẹ ede ti nfi ọgbọn kọ wọn silẹ.

"Awon wọ yi yio wa ona lati sọ arawọn di ajihin rere ti ọkan wọn yio mọ lati mojuto alafia gbogbo enia p pa wọn oşişẹ ẹgbẹ, onisowo ati awọn ọdọ.

"A şe ọkan giri lati jẹki awọn enia mọ nipa alafia f n vb gbo enia ati ohun ti o fa ipo ti nwọn wa lori isoro nwọn nafi suru so fun wọn ọgbọn ti ka ba ofin mu ti nwọn fi nba Ijọba wa lorik ti ko dara p ẹgb. Afẹkiijẹmọjẹ ki a yẹ, apania ni w g geb ẹgbẹ Dẹmo ati Olomi ti nşe şu-gbon a n l ti duro lori igbagbo ti awon ohun ti a yan pẹlu iduroşinşin.

"Iwa yi yio jẹki a l gbara nitoripe yio jẹ i a yaju ọbẹ lara iyan ẹyi t rorun fun awọn aşoju ota wa t wa n arin wa orin ẹgbẹ wa fun atunşe ẹgbẹ yio sisẹ ri-bibi nibi gbogbo wa yo ko awon en a jo lati p rapo ki a si lodi si Ijọba ti awon kan nd ri rẹ yi i.

# Kere o Kere o Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanşoh nou Egbogi ani LEOPILLS awa na ulo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na ujẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi şe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nşe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ojo rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti ami di tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igb nsẹ deede, inurirun ngbakugba ara wiwo, Ẹsanro ehin didun s sa ati aiko ritan kede e ko d ro buruku lara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbi pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kia kia ti nwọn nba lo egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ şe lara enia nipa sis di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla si e mẹfa abo (6/-6 pere Igo kekere şile mẹta abo (3/6) pere. Ber Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ n Şọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos

## Iwo Ha Nfẹ Ile L'Eko Bi

| | |
|---|---|
| Room | £3 |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room / Parlour | £6 |
| Room / Shop | £15 |
| Flat (Lagos) | £20 |
| Flat (E.B) | £25 |

Ti o ba nfẹ okan ninu awọn ile wọnyi yara tete lọ ri Ọgbẹni ODUSI — 178 Bamgboşe Street Lagos. ni deede agogo merin irọlẹ si agogo mẹfa irọlẹ ijafara lewu anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,560 TUESDAY NOVEMBER 16, 1965 (2)


## Awon Ata'we Irohin Kesi Gomina

IBADAN:— Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni ọjọ Iṣẹgun ti ijọ ọjọ kẹsan oṣu yi ni awọn ẹgbẹ Olutawe irohin ilu Ibadan awọn ti a npe ni "Ibadan News Vendors Association" kesi Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye Joseph Ọdẹleyẹ Fadahunsi lati lo ipo rẹ rere ki o ba wọn kesi Ijọba ibilẹ ilu Ibadan lati jeki awọn iwe irohin meje ti nwọn sọ pe ko gbọdọ wọ ilu Ibadan ati agbegbe rẹ le ma de ilu na,

Awọn ẹgbẹ Olutawe irohin na se alaye wọnyi lori ofin kan ti Ijọba ibilẹ na gbe jade ninu Ipade kan ti nwọn ṣe ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ karun oṣu yi pe awọn iwe irohin na ko gbọdọ wọ ilu Ibadan tabi pe ki nwọn ma ka ni ile ati ti agbegbe rẹ eyiti awọn Igbimọ na se alaye pe o lodi si ofin,

Awọn iwe irohin meje ti awọn Igbimọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Ibadan na ṣe alaye pe ko gbọdọ wọ ilu Ibadan ati agbegbe rẹ ni West African Pilot, Nigerian Tribune Nigeria Outlook, Daily Telegraph, Irohin Yoruba, Irohin Imọlẹ ati iwe irohin Daily Comet.

# AWỌN OBINRIN IBADAN F'ABUKU KAN ỌLỌPA!

IBADAN:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni awọn obinrin ilu Ibadan ti bu ẹnu atẹ lu awọn ọlọpa ti nwọn ko si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati papa ni ilu Ibadan lori eto abayọri idi bo si ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati jẹki eto alafia wa ni Ipinlẹ ati pe awọn obinrin na tun ṣe alaye gl o pe ti awọn ọlọpa ti ṣe nhuwa ni Ipinlẹ na tabi ni ilu Ibadan ni ko tọna ti bi ba oju mu.

Ninu ọrọ olori awọn obinrin ọlọja ilu Ibadan Iya-Afin A Adegbuyi ni o ti ṣe alaye lori bi ọga agba awọn ọlọpa ti nwọn ko wa si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati Ipinlẹ Ariwa ni o ti ṣe alaye pe ki iṣe ohun ti wọn ran awọn ọlọpa na ni wọn wa se ni Ipinlẹ na bikoṣe wipe awọn ọlọpa na wa lati da ilu na ru ati pe ki iṣe wipe nwọn wa lati ṣe gẹgẹbi eto alafia yio ṣe pada si Ipinlẹ na,

Iya afin Adegbuyi tun ṣe alaye pe awọn ọlọpa lati Ilẹ Ariwa na tun wa lati wa mu na awọn obinrin ọlọja ilu Ibadan ati pe fun ọpọlọpọ ọkọ ti awọn obinrin ọlọja ba fẹri ọga agba awọn ọlọpa ki yio fun wọn laye bikoṣe wipe nwọn yio fi ko ndo wọn ma na awọn obinrin ọlọja ti wọn ko ni fun wọn laye lati ri ọga agba awọn ọlọpa na.

Iyaafin A. Adegbuyi fi ye awọn oniwe irohin to wa sibi ipade kan to ba awọn oniwe irohin na ṣe ni ilu Ibadan ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kerinla oṣu yi pe awọn ẹgbẹ on kesi Ọga agba awọn ọlọpa ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Ọgbẹni Louis Edet ati Ọga agba fun awọn Ọlọpa ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni Ọlọfin Bello lati lo ipo wọn rere ki o tete mu oju to iru iwa ti awọn Ọlọpa to wa ni Ipinlẹ na ati paapa julọ ni ilu Ibadan ma nhu nipa pe ki nwọn ma lu awọn Obinrin Ọlọja lọna ti ko tọ.

## Lati Oju Ewe Kini

Awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre alaye pe eleyi ti fi han gban gban pe ẹgbẹ itẹsiwaju (U P G A) lo bori ibo si ile Igbimọ aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to kọja lọ yi



Alhaji D. S. Adegbenro

Awon omo ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Eko ṣe alaye pe eleyi si ti fi han pe egbe itesiwaju UPGA lo bori idibosi ile Igbimo Aṣofin Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria ati egbe Demo si ja egbe U P G A lole lati le so wipe awon lo bori ibo si ile Igbimọ Aṣofin Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria

Awon egbe na tun ṣe alaye pe pe eleyi si ti fi hangba ngba pe ko si egbe Demo ta bi egbe Olomi (NPC) ni ilu Eko nwon tun ṣe alaye pe nitori pe awon egbe olowo NNDP ati olomi NPC timo pe won ko le ri aye ṣe ma daru ninu ibo si ile Igbimo Ijoba ibile ilu Eko lo mu won so wipe awon ko dibo mo ninu idibo na

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe ebogbo awon aṣoju egbe Demo ninu idi bo si ile Igbimo ti Ijoba Ibi le ilu Eko lo je wipe nwon padanu owo asan tele won ninu ibo na



Dokita M. I. Okpara

# AKIYESI

Eleyi ni lati fi ye ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ni ilẹ DAHOMEY pe ti ẹba fẹ ra Irohin Imọlẹ ki ẹlọ si ọdọ Ọgbẹni L. M Adesanmiyan ONIFAJI DAHOMEY, PORTNOVO.

Tete yara lọ ra iwe tirẹ lọdọ rẹ ki o le gbadun irohin Oloyinmọmọ ninu iwe Irohin Imọlẹ ati nipa bi nkan ti nlọ si ni ilẹ Naijiria paapa julọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Irohin ko to afojuba,

**OLOTU**

## Akiyesi

Eyi ni lati fi yeẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ pe ẹlun ọrọ lori Rogbodiyan ẹgbẹ Afẹnifẹre lati ẹnu akọwe Agba ẹgbẹ na Ọgbẹni S, G. Ikoku ti o wa ni Ghana nisisiyi ti bẹrẹsi jade ninu iwe wa lati oni lọ, ẹ wo ọju ewe keji.

Tete yara lọ ra iwe Irohin Imọlẹ tirẹ loni ki o si ka ọrọ na Oyinmọmọ na.


Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985 Editor: TUNJI ADEOSUN 45' Campbell Street Lagos. 16/11/65